
Láti Ọwọ́ Ààrẹ
Thomas S. Monson



# Dúró Gẹ́gẹ́bí Ìmọ́lẹ̀ Kan

Mo ti ní ànfàní lílọ sí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ayẹyẹ ọ̀lájú tí wọ́n ṣe papọ̀ pẹ̀lú àwọn ìyàsímímọ́ tẹ́mpílì. Mo ti fẹ́ràn gbogbo wọn, pẹ̀lú ìkan tí wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ ṣe láìpẹ́ tí mo lọ sí ní Phoenix, Arizona, USA, ní Oṣù Kọ́kànlá tó kọjá.

Àwọn ọ̀dọ́ Ènìyàn Mímọ́ Ọjọ́ ìkẹhìn tó kópa nínú àwọn ayẹyẹ ọ̀lájú náà ṣe àwọn ètò ìyanu, onírántí. Lọ́dún tó kọjá ní Phoenix, ní kété ṣíwájú ayẹyẹ náà, mo sọ fún àwọn olùkópa, "Ẹ jẹ́ àwọn ọmọ ìmọ́lẹ̀."

Mo máa fẹ́ kí gbogbo ọ̀dọ́ Ìjọ mọ̀ pé wọ́n jẹ́ àwọn ọmọ ìmọ́lẹ̀. Ní ìdí èyí, wọ́n ní ojúṣe kán láti jẹ́ "gẹ́gẹ́bí ìmọ́lẹ̀ nínú ayé" (Àwọn Ará Fílípì 2:15). Wọ́n ní ojúṣe kan láti pin àwọn òtítọ́ ìhìnrere. Wọ́n ní ìpè kan láti dúró gẹ́gẹ́bí àsíá kan ti tẹ́mpílì, ní fífi ìmọ́lẹ̀ ìhìnrere hàn sí ayé òkùnkùn tó ńpọ̀ si. Wọ́n ní ọ̀rọ̀ ìyànjú láti jẹ́ kí ìmọ́lẹ̀ wọn máa tàn kí ó sì máa jó jerejere.

Kí a bá lè jẹ́ "àpẹrẹ àwọn onígbàgbọ́" (1 Tímótì 4:12), àwa fúnra wa gbọ́dọ̀ gbàgbọ́. A gbọ́dọ̀ mú ìgbàgbọ́ tó kanpá dàgbà si látì wà layè nípa ti ẹ̀mí àti láti jẹ́ ìmọ́lẹ̀ kan fún àwọn ẹlòmíràn. A gbọ́dọ̀ ṣìkẹ́ ẹ̀rí wa títí tí yíò fi di ìdákòró sí ayé wa.

Nínú àwọn ọ̀nà tó dára jù láti jèrè àti láti pa ìgbàgbọ́ tí a nílò lóní mọ́ ni láti kà kí a sì ṣàṣàrò àwọn ìwé mímọ́ àti láti gbàdúrà léraléra àti lemọ́lemọ́. Sí àwọn ọ̀dọ̀ Ìjọ, mo sọ pé, tí ẹ kò bá tîì ṣe bẹ́ẹ̀, ẹ mú ìwà ṣíṣe àṣàrò nínú ìwé mímọ́ áti gbígba àdúrà lójoojúmọ́ dàgbà si nísisìyí. Láìsí àwọn ìṣe méjèjì pàtàkì yí, àwọn agbára ìta àti pé nígbàmíràn àwọn òtítọ́ líle ti ayé lè bòó mọ́lẹ̀ tàbí àní kí ó pa ìmọ́lẹ̀ yín.

Àwọn ọdún ìgbà èwe kò rọrùn. Wọ́n jẹ́ àwọn ọdún ìbẹ̀rẹ̀ nígbàtí Sátánì yíò dán an yín wò tí yíò sì sa gbogbo ipa rẹ̀ láti tàn yín kúrò lọ́nà èyí tí yíò darí yín padà sí ilé yín ọ̀run. Ṣùgbọ́n bí ẹ bá ṣe nkáà tí ẹ sì ngbàdúrà àti bí ẹ bá ṣe nṣiṣẹ́ sìn tí ẹ sì ṣe ìgbọ́ran, ẹ̀yin yíò wá mọ̀ dáradára si "ìmọ́lẹ̀ èyítí ó ntàn nínú òkùnkùn" (D&C 6:21), Alápẹrẹ wa àti agbára wa — àní Jésù Krístì Olúwa. Òun ni Ìmọ́lẹ̀ náà tí a níláti gbámú láti tú àkójọpọ̀ òkùnkùn ká (Wo 3 Nífáì 18:24).

Pẹ̀lú ẹ̀rí kàn tó lágbára nípa Olùgbàlà àti ìmúpadàbọ̀sípò ìhìnrere Rẹ̀, ẹ ní àìlópin àwọn ànfàní láti tàn bí Ìmọ́lẹ̀. Wọ́n yíì yín ká lójoojúmọ́, nínú ipòkípò tí ẹ lè bá ara yín. Bí ẹ bá ṣe ntẹ̀lé àpẹrẹ Olùgbàlà, tiyín yíò jẹ́ ànfàní láti jẹ́ ìmọ́lẹ̀ kan, gẹ́gẹ́bí ó ti wà, nínú ìgbé ayé àwọn wọnnì ní àyíká yín—bóyá wọ́n jẹ́ áwọn ọmọ ẹbí ti ara yín, áwọn ojúgba yàrá ìkàwé, áwọn ará ibi iṣẹ́, áwọn olùbárin lásán, tàbí áwọn àjèjì pátápátá.

Nígbàtí ẹ bá jẹ́ ìmọ́lẹ̀ sí ayé, àwọn ènìyàn láyíká yín yíò ní ìmọara ti ẹ̀mí pàtàkì kan tí yíò mú wọn nífẹ́ láti báa yín rẹ́ àti láti tẹ̀lé àpẹrẹ yín.

Mo bẹ̀bẹ̀ pẹ̀lú àwọn òbí àti àwọn olórí ọ̀dọ́ wa láti ràn wọ́n lọ́wọ́ láti dúróṣinṣin fún òtítọ́ àti òdodo. Ṣèrànwọ́

láti ṣí ilẹ̀kùn ìkẹ́kọ́ sílẹ̀ gbalasa sí ìwọ̀ wọn, nípa lílóye, àti nípa iṣẹ́ ìsìn nínú ìjọba ti Ọlọ́run. Gbé agbára sínú wọn láti tàpá sí àwọn àdánwò ayé. Fún wọn ní ìfẹ́ láti rìn nínú ìwà ọ̀run àti ìgbàgbọ́, láti jẹ́ olùgbàdúrà, àti láti wo ọ̀run gẹ́gẹ́bí ìdákòró lemọ́lemọ́ fún wọn.

Sí àwọn ọ̀dọ́ wa, mo sọ pé, Bàbá wa Ọ̀run nífẹ́ yín. Njẹ́ kí ẹ ní ìmọ̀ara ìfẹ́ báknnáà èyí tí àwọn olóyè Ìjọ ní fún un yín. Njẹ́ kí ẹ ní ìfẹ́ làti sìn Bàbá yín Ọ̀run àti Ọmọ Rẹ̀ títí láeláé. Àti pé kí ẹ máà rìn nígbàgbogbo nínú òtítọ́ àti kí ẹ dúró bí ìmọ́lẹ̀ kan ní ààrín àwọn ọmọ Ọlọ́run.

---

**Ẹ̀KỌ́ KÍKỌ́ LÁTINÚ Ọ̀RỌ̀ YÍ**

Gbèrò sísọ̀rọ̀ pẹ̀lú àwọn wọnnì tí ẹ̀ nkọ́ ni ohun tí ó túmọ̀ sí láti jẹ́ "[ọmọ] ìmọ́lẹ̀ kan." Kíni àwọn ojúṣe tí ó yẹ kí a ṣe? Ẹ lè sọ àwọn ìgbàkan nígbàtí ìmọ́lẹ̀ ti tàn gidi gan an àti ohun tí ó múu tàn. Gbèrò bíbèèrè lọ́wọ́ wọn ronú nípa ẹnìkan pàtó, gẹ́gẹ́bí irú ọ̀dọ́ kan, ará ibi iṣẹ́, tàbí ọmọ ẹbí wọn, tí ó lè wà nínú àìní ìmọ́lẹ̀. Nígbànáà ẹ lè gbàdúrà papọ̀ nípa ọ̀nà kan láti pín ìmọ́lẹ̀ pẹ̀lú ẹni náà.

## Ọ̀DỌ́

### Àsíá Ìmọ́lẹ̀

Àarẹ Monson kọ́ni pé àwọn ọ̀dọ́ Ìjọ "ní ipè kan láti dúró bí àsíá tẹ́mpìlì kan, tó nfi ìmọ́lẹ̀ ìhìnrere hàn sí ayé òkùnkùn tó npọ̀ si." Ó fúnni ni àwọn ọ̀nà díẹ̀ tí a fi lè ṣe èyí:

Ṣe àbápín ìhìnrere
Gbàgbọ́
Mú ìgbàgbọ́ dàgbà si
Jẹ́ ìmọ́lẹ̀ kan sí àwọn ẹlòmíràn
Ṣìkẹ́ ẹ̀rí rẹ títí tí yíò fi di ìdákòró kan sí ìgbésí ayé rẹ
Kàá kí o sì ṣàṣàrò nínú àwọn ìwé mímọ́
Gbàdúrà lemọ́lemọ́ àti léraléra
Sìn
Gbọ́ran

Gbèrò fífi ara rẹ lé oṣùwọ̀n láti ìkínní títí dé ìkárùn nínú ìkọ̀ọ̀kan ti àwọn ibí wọ̀nyí. Fún àwọn ibí tó wà pẹ̀lú ìgbésẹ̀ tó lọlẹ̀ jù, ẹ lè ṣàṣàrò àwọn àkórí wọ̀nyí nínú àwọn ìwé mímọ́ tàbí ṣàwárí wọn. LDS.org. Lẹ́hìn tí ẹ bá ti ṣàṣàrò àwọn àkórí wọ̀nyí, ẹ lè ronú àwọn ọ̀nà tí ẹ fi lè fún àwọn ibi wọ̀nyí lókun kí ẹ sì gbé àwọn ìfojúsí kalẹ̀ láti ṣe bẹ́ẹ̀.

## ÀWỌN ỌMỌ

### Ẹ Tan Ìmọ́lẹ̀ Yín

Gẹ́gẹ́bí ọmọ Ọlọ́run, ọmọ ìmọ́lẹ̀ ni ìwọ í ṣe. Ẹ lè jèrè ìmọ́lẹ̀ síi nípa títẹ̀lé Olùgbàlà wa, Jésù Krístì. Jésù Krístì àti Bàbá Ọ̀run nífẹ́ yín wọ́n sì fẹ́ kí ẹ tàn fún àwọn ẹlòmíràn àti pé kí ẹ darí wọn sí Krístì. Ẹ lè tàn lásán nípa jíjẹ́ ara yín nígbàtí ẹ bá tẹ̀lé àwọn òfin, bíi gbígbàdúrà àti kíkà àwọn ìwé mímọ́. Ẹ ya àwọn àwòrán ìràwọ̀ díẹ̀ sórí ìwé kí ẹ sì kọ ọ̀rọ̀ síwọn lórí pẹ̀lú àwọn èrò ti bí ẹ ṣe lè tàn fún àwọn míràn gẹ́gẹ́bí àpẹrẹ ti Jésù Krístì (fún àpẹrẹ, "lílọ sí ìjọ," tàbí "ríran ẹbí mi lọ́wọ́").

© Ọdún 2015 látọwọ́ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. A tẹ̀ẹ́ ní USA. Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/15. Àṣẹ Ìyírọ̀padà: 6/15.
Ìyírọ̀padà ti *First Presidency Message, August 2015*. Yoruba. 12588 779

# Ìhùwàsí Tọ̀run ti Jésù Krístì: Ọlọ́kàn Tútù àti Onírẹ̀lẹ̀

*Ẹ fi tàdúràtàdúrà ṣàṣàrò ohun èlò yí kí ẹ sì ṣàwárí láti mọ ohun tí ẹ ó pín. Báwo ni líl óye ìgbé ayé àti áwọn ojúṣe Olùgbàlà ṣe nmú ìgbàgbọ́ yín nínú Rẹ̀ pọ̀ síi kí ẹ sì bùkún àwọn wọnnì tí ẹ̀ nṣe ìtọ́jú lórí nípa ìbẹniwò kíkọni? Fún ìwífúnni síi, lọ sí reliefsociety.lds.org.*

**Ìgbàgbọ́, Ẹbí, Ìrànlọ́wọ́**

*Èyí jẹ́ apákan onírurú ti àwọn Ọ̀rọ̀ Ìbẹniwò Kíkọ́ni tó ńfarahàn nínú áwọn ìhùwàsí tọ̀run ti Olùgbàlà.*

Jésù sọ pé, "Ẹnití ó bá tóbi jù nínú yín kí ó jẹ́ àbúrò; ẹnití ó sì ṣe olórí, bí ẹnití nṣiṣẹ́ sìn. Nítorí tani ó tóbi jù, ẹnití ó jókó ti oúnjẹ, tàbí ẹnití ó nṣiṣẹ́ sìn? ẹnití ó jókó ti oúnjẹ ha kọ́? ṣùgbọ́n èmi nbẹ láárín yín bí ẹnití nṣiṣẹ́ sìn" (Luke 22:26–27).

"Olùgbàlà ni àpẹrẹ wa tó ga jùlọ níti agbára ìrẹ̀lẹ̀ àti ìrẹ ara ẹni sílẹ̀. Lẹ́hìn gbogbo rẹ̀, fífi ìfẹ́ ara Rẹ̀ sílẹ̀ fún ti Bàbá, mú èyí tí ó tóbi jùlọ, àní ìṣẹ̀lẹ̀ inú gbogbo ìwé ìtàn, èyítí ólágbára jùlọ wáyé. Bóyá díẹ̀ lára àwọn ọ̀rọ̀ tó jẹ́ mímọ́ jùlọ nínú gbogbo àwọn ìwé mímọ́ kàn jẹ́ pé 'Ìfẹ́ ti èmí kọ́, bíkòṣe tìrẹ ni, kí a ṣe' (Luke 22:42)."[1]

Gẹ́gẹ́bí àwọn ọmọ ẹ̀hìn ti Jésù Krístì, à nfi ìgbàgbogbo wá láti dàbíi Rẹ̀. "Ọkàn tútù ṣe pàtàkì fún wa láti dàbíi ti Krístì síi," ni Alàgbà Ulisses Soares ti Àádọ́rin sọ. Láìsí bẹ́ẹ̀ a kò ní lè mú àwọn ìwà ọ̀run pàtàkì míràn dàgbà si. Jíjẹ́ ọlọ́kàn tútù kò túmọ̀ sí àìlera, ṣùgbọ́n ó túmọ̀ sí híhùwà pẹ̀lú inúrere àti ìwàrere, fífi agbára hàn, dídákẹ́ rọ́rọ́, ìlera yíyẹ araẹni, àti ìkóraẹni níjánu."[2] Bí a ṣe nṣiṣẹ́ láti mú ìhùwàsí yí dàgbà si, a ó ri wípé "fífi ìrẹ̀lẹ̀ jọ̀wọ́ ìfẹ́ ara wa sílẹ̀ fún Bàbá yíò ṣàmúwá ìfúnilágbára Ọlọ́run sí wa— agbára ìrẹ̀lẹ̀. Ó jẹ́ agbára láti pàdé àwọn ìpọ́njú ayé, agbára àláfíà, agbára ìrètí, agbára ti ọkàn tó ńsọ kúlúkúlú pẹ̀lú ìfẹ́ kan fún àti ẹ̀rí Jésù Krístì Olùgbàlà, àní agbára ìràpadà."[3]

## Àfikún Àwọn Ìwé Mímọ́

Mátteù 26:39; Jòhánù 5:30; Mòsíàh 3:19; Hẹ́lámánì 3:35

## Látinú àwọn Ìwé Mímọ́

Ọ̀kan nínú àwọn àsìkò tó ládùn jùlọ àti tí ó alágbára jùlọ̀ nípa iṣẹ́ ìránṣẹ́ Krístì ni ìgbàtí Ó wẹ ẹsẹ̀ àwọn ọmọ ẹ̀hìn Rẹ̀. "Ó dìde ní ìdí oúnjẹ alẹ́, ó sì fi agbádá rẹ̀ lẹ́lẹ̀ sí apákan; ó sì mú gèlè, ó di ara rẹ̀ ní àmùrè. Lẹ́hìn náà ó bu omi sínú awokòtò kan, ó sì bẹ̀rẹ̀ sí í wẹ ẹsẹ̀ àwọn ọmọ ẹ̀hìn rẹ̀, ó sì nfi gèlè tí ó fi di àmùrè nù wọ́n (John 13:4–5).

Bí Olùgbàlà ṣe ńfi ìlànà yí hàn, àwọn ọmọ ẹ̀hìn lè ti ní ìmulómi ọkàn pé Olúwa wọn àti Olùkọ́ni nkúnlẹ̀ níwájú wọn tí ó sì nṣe iṣẹ́ ìsìn ọlọ́kàn tútù gidi kan. Nígbànáà Jésù ṣàlàyé àwọn ẹ̀kọ́ tí Ó fẹ́ kí wọn àti gbogbo wa kọ́:

"Njẹ́ bí èmi, tí íṣe Olúwa àti Olùkọ́ni yín, bá wẹ ẹsẹ̀ yín, ó tọ́ kí ẹ̀yin pẹ̀lú sì máa wẹ ẹsẹ̀ ara yín.

"Nítorí mo ti fi àpẹrẹ kan fún yín, kí ẹ̀yin kí ó lè má ṣe gẹ́gẹ́bí mo ti ṣe síi yín" (John 13:14–15).

**ÀWỌN ÀKỌSÍLẸ̀ RÁNPẸ́**

1. Richard C. Edgley, "Ìfúnni lágbára ti Ìrẹ̀lẹ̀," *Atọ́nà,* Oṣù Kọ́kànlá. Ọdún 2003, 99.
2. Ulisses Soares, "Jẹ́ Ọlọ́kàn Tútù àti Onírẹ̀lẹ̀ Ọkàn," *Atọ́nà,* Oṣù Ìkọkànlá. Ọdún 2013, 9.
3. Richard C. Edgley, "Ìfúnni Lágbára ti Ìrẹ̀lẹ̀," 99.

### Gbèrò Èyí

Báwo ni níní ìrẹ̀lẹ̀ ṣe nràn wá lọ́wọ́ láti ní ìfẹ́ bíi ti Olùgbàlà?

© Ọdún 2015 látọwọ́ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. A tẹ̀ẹ́ ní USA Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/15. Àṣẹ Ìyírọ̀padà: 6/15.
Ìyírọ̀padà ti *Visiting Teaching Message, August 2015.* Yoruba. 12588 779